## ṢÍṢE ÌGBÉLÉWỌ̀N FÚN DÁÀṢÌ

Ní àsìkò ìrúwé (spring) ti 2002, a ṣe àtúnṣe bí a óò ṣe máa ṣe ìgbéléwọ̀n dáàṣì. Àtúnṣe tuntun yìí jẹ́ èyí tó rí bí i ti tẹ̀lẹ̀ àmọ́ ó rọrùn láti lò ju ti àtẹ̀yìn wá lọ; kò sì lọ́jú pọ̀ rara bí a kò bá rí détà kan. Fún ìdí èyí, a gbà ọ̀nà tuntun yìí; àmọ́ o, eyikeyii ìlànà tí ẹ bá lò yóò fún ní èsì kan náà.

Ọ̀nà méjì ní a fi máa ṣe ìgbéléwọ̀n yìí: ailera/iye ìbéèrè (30 items, scored 1-5) àti àwọn eré ìdárayá tí ó ṣe daadaa/orin tàbí ìpín iṣẹ́ (4 items, scored 1-5).

## ÀÌLERA/MÁÀKÌ ÀPẸẸRẸ

Ó kéré tán mẹ́tàdínlọ́gbọ̀n ninu ọgbọ̀n ìbéèrè ni ó gbọ́dọ̀ di dídáhùn kí á tó lè ṣe ìṣirò. Àwọn nọ́mbà fún gbogbo ìdáhùn ni a óò rò pọ̀, tí a óò si ṣe àròpín/afúréèjì rẹ̀; èyí tí yóò jẹ́ ẹyọ kan kan ninu marun-ún. Nọ́mbà yìí ni yóò di ẹyọ kan ninu ọgọ́rùn-ún nipa yíyọ óókàn àti sísọ ọ́ dọ̀pọ̀ pẹ̀lú márùn-ún dín ní ọgbọ̀n. Èyí wà fún mímú kí ó rọrùn láti ṣe àmì rẹ̀ pẹ̀lú àwọn yòókù tí ó wà lórí ìgbéléwọ̀n óókan sí ọgọ́rùn-ún. Ibi tí àmì bá ti pọ̀ jù ń sọ̀rọ̀ nipa bí àìlera ti pọ̀ tó.

Àìlera dáàṣì/àmi àpẹẹrẹ $\left[\left(\frac{\text{àpapọ̀ iye ìdáhùn}}{n}\right)-1\right] \times 25$

n dúró fún iye gbogbo ìdáhùn tí olùdáhùn dáhùn

Máàkì dáàṣì lè má di ṣíṣírò bí ó bá ju mẹ́ta lọ tí olùbéèrè ò bá dahun.

## ÀWỌN MÓDÙLÙ TÍ KÒ PỌN DANDAN (ERÉ ÌDÁRAYÁ/ORIN TÀBÍ IṢẸ́)

Módùlù Kọ̀ọ̀kan tí kò pọn dandan ní ohun mẹ́rin, ti ènìyàn lè lò tàbí kó má lò nítorí irúfẹ́ àwọn ìbéèrè náà. Èròngbà àwọn módùlù tí kò pọn dandan wà fún mímọ àwọn ìṣòro pàtó tí àwọn tó fi iṣẹ́ eré sísá ṣe ojúlówó iṣẹ́ wọn/eré ṣíṣe tabí àwọn ọ̀wọ́ òṣìṣẹ́ yòókù lè ní àmọ́ tì kò lè fa ìdíwọ́ fún iṣẹ́ òòjọ́ wọn; èyí tó sì lè má hàn nínú àwọn ọgbọ̀n èròjà dáàṣì.

Ọ̀nà kan náà tí a mẹ́nu bà lókè yìí náà ni a óò tẹ̀lé láti fi ṣírò àwọn ibeere mẹ́rin tó wà nínú módùlù tí ò pọn dandan. Ṣírò gbogbo nọ́mbà tí a fún àwọn ìdáhùn kọ̀ọ̀kan, kí o sì pín pẹ̀lú mẹ́rin (iye ìbéèrè); yọ óókan kúrò kí o sì sọ ọ́ dọ̀pọ̀ pẹ̀lú márùn-ún dín ní ọgbọ̀n láti ní iye kan nínú ọgọ́rùn-ún.

# IYE ÀLÀFO

Tí olùdáhùn bá fo ìdá mẹ́wàá nínú ọgọ́rùn-ún (èyí tó túnmọ̀ sí pé ó ju mẹ́ta lọ), o kò lè ṣírò àìlera dáàṣì/àmi àpẹẹrẹ. Pẹ̀lú òfin yìí bákan náà (èyí tó túnmọ̀ sí pé kò gbọdọ̀ ju ìdá mẹ́wàá nínú ọgọ́rùn-ún tí ó wà ní àfo tàbí àìdáhùn), kò gbọdọ̀ sí nǹkan kan tí kò sí ní dídáhùn nínú módùlù àwọn tó ń fi iṣẹ́ eré sísá ṣe ojúlówó iṣẹ́ wọn/eré ṣíṣe tabí àwọn ọ̀wọ́ òṣìṣẹ́ yooku nitori ohun mẹ́rin pere ni ó wà nínú módùlù yìí. Òfin ohun tó wà ní fífò yìí jẹ́ èyi tó pọn dandan fún àkọ́ṣe àti àtúnṣe ìgbéléwọ̀n dáàṣì yìí.

Institute for Work & Health 481
University Ave., Suite 800
Toronto, ON Canada M5G 2E9
Phone: (416) 927-2027 ext. 2173
Fax: (416) 927-4167
E-mail: dash@iwh.on.ca
Web site: www.dash.iwh.on.ca

Institute for Work & Health | Research Excellence Advancing Employee Health

© INSTITUTE FOR WORK & HEALTH 2006. ALL RIGHTS RESERVED.